# ỌMỌ-ỌWỌ́ NINU KRISTI
## Heberu 5:12-14; 6:1-12.
## ẸKỌ 437 – FUN AWỌN ỌDỌ

**AKỌSORI: "Ṣugbọn ipa-ọ̀na awọn olõtọ dabi titàn imọlẹ, ti o ntàn siwaju ati siwaju titi di ọsangangan" (Owe 4:18).**

Awọn eniyan ti o ba jẹwọ ẹ̀ṣẹ wọn ti wọn si fi ọkàn wọn fun Oluwa ni awọn ti a tunbi, a bi wọn sinu igbesi-ayé titun. Bibeli sọ fun wa pe nigba ti eniyan ba di Onigbagbọ o di "ẹda titun" (2 Kọrinti 5:17). Paulu pẹlu pe awọn ti o ṣẹṣẹ di Onigbagbọ ni "ọmọ-ọwọ ninu Kristi" (1 Kọrinti 3:1). Wọn ṣẹṣẹ bẹrẹ irin-ajo ti Onigbagbọ́ ni, ko yẹ ki a ro pe wọn ti mọ ohun gbogbo nipa ẹsin-igbagbọ́.

### Bibẹrẹ gẹgẹ bi Ọmọ-ọwọ́

A ko sọ eleyi lati fi bu ẹnikẹni kù pe o ti jẹ́ ọmọ-ọwọ́ nigba kan ri; olukuluku eniyan ni o bẹrẹ igbesi-ayé rẹ̀ gẹgẹ bi ọmọ-ọwọ́. Ṣugbọn ko si ẹni ti o wà ni ọmọ-ọwọ́ fun igba pipẹ; awọn ọmọ-ọwọ́ miiran le ni arun ti yoo jẹ́ idiwọ fun didagba wọn, wọn a si rán mọ́lẹ̀. Tabi ki iru aisan miiran ṣe idiwọ fun awọn miiran ki o ma si jẹ ki wọn le rin, to bẹẹ ti wọn yoo jẹ́ alailera titi ọjọ-ayé wọn. Ṣugbọn awọn nnkan bawọnnni jẹ́ awọn jamba ti olukuluku eniyan n yẹra fun.

Bakan naa ni awa ko fẹ jẹ́ ọmọ-ọwọ́ nipa ti igbesi-ayé Onigbagbọ́. A fẹ jẹ́ Onigbagbọ́ alagbara, onilera, ti o si dagba soke -- Onigbagbọ́ ti o le doju kọ iṣoro, awọn ti ko fà sẹyin nigba ti awọn ohun idayafo ba ṣẹlẹ si wọn, tabi nigba ti eṣu ba n gbiyanju lati fi ifẹ ohun ayé tan wọn jẹ. Awọn onilera Onigbagbọ́ gbọdọ jẹ ounjẹ ti o dara, ounjẹ wa si ni Ọrọ Ọlọrun. Awa mọ eyi, nitori Jesu wi pe: "Emi li onjẹ iye: ẹnikẹni ti o ba tọ̀ mi wá, ebi ki yio pa a; ẹniti o ba si gbà mi gbọ́, ọrùngbẹ ki yio gbẹ ẹ mọ́ lai" (Johannu 6:35). Nibomiran a sọ fun wa pe "Ọ̀rọ na si di ara, on si mba wa gbé" (Johannu 1:14), eyi ti i ṣe Jesu. Nitori naa ọna ti o ṣi silẹ fun wa lati dagba ati lati di Onigbagbọ́ alagbara ni lati kọ́ Ọrọ Ọlọrun pẹlu ironu. Ọmọ-ọwọ́ onilera n fẹ́ ọpọlọpọ wàrà, bakan naa ni Onigbagbọ́ onilera "fẹ wàra ti Ẹmi na eyiti kò li ẹ̀tan" ki oun le maa ti ipasẹ rẹ̀ dagba (1 Peteru 2:2).

### Jijẹ Ẹran

Lẹyin oṣu diẹ ti a bi ọmọ-ọwọ́, wàra kò ni tẹ́ ẹ lọrun mọ́, nitori naa a oo maa fun un ni ẹran ti a ti lọ̀ mulọmulọ; lẹyin eyi, nigba ti o bá dagba tó ẹni ti o le jẹ ẹran, a oo maa fi ẹran rẹ̀ lé e lọwọ. Kò ha tọ́ ki Onigbagbọ́ paapaa dagba lọna bayii – lati maa jẹ "onjẹ lile" nì dipo ki o maa mu wàra? Itumọ eyi ni pé oun yoo di ẹni ti yoo le ni ifi-ara-rubọ ti o jinlẹ pupọ. Oun yoo ni igboya lati mú iduro ti o yege lori awọn ilana inu Bibeli ti o le koko, oun yoo si ni agbára si i lati le bori ẹ̀ṣẹ. Ifẹ Ọlọrun yoo si jinlẹ si i ninu ọkàn rẹ̀.

Nigba ti awọn ọmọde ti kò tó ọ lọjọ ori ba n fẹ bá ọ ṣire, iwọ ha wi fun wọn rí pé, "Iwọ kere si mi pupọ"? Iwọ ha ti gbiyanju lati yẹra fun awọn ọmọ wẹ́wẹ́ nigba ti wọ́n ba n fẹ so mọ́ ọ? Iwọ kà wọ́n si ohun iyọnu; ṣugbọn nigba ti wọ́n bá dagba tán ti wọn si ni ohun ti iwọ rò pé ó mú ọgbọ́n lọwọ, iwọ a si ni itẹlọrun lati bá wọn kẹgbẹ pọ̀.

Bawo ni iwọ ti ni idagbasoke tó nipa ti ẹmi lati igba ti Oluwa ti gba ọkàn rẹ là? Iwọ ha ti kọ́ lati ni "ọgbọ́n si i," tabi iwọ si tún wà bi "alailọgbọn kan"? Paulu wi pé: "onjẹ lile ni fun awọn ti o dagba, awọn ẹni nipa iriri, ti nwọn nlò ọgbọ́n wọn lati fi iyatọ sarin rere ati buburu" (Heberu 5:14). Kò ṣẹṣẹ digba ti awọn ọmọde bá dagba tán ki wọn to mọ Ọrọ Ọlọrun dé àye ti wọ́n fi le kọ́ awọn ẹlomiran. Ṣugbọn gbigbọ́ Ọrọ yii nikan kò le fun wa ni ọgbọ́n nipa ti ẹmi. A gbọdọ fi Ọrọ naa ṣe odiwọn igbesi-ayé wa bi a bá fẹ́ "mã dàgba ninu ore-ọfẹ ati ninu imọ Oluwa ati Olugbala wa Jesu Kristi" (2 Peteru 3:18).

Nigba ti Paulu Apọsteli n kọwe si awọn Heberu Onigbagbọ́ o wi pé eti pupọ ti "yigbì ni gbigbọ́." O le jẹ pe wọ́n ti gbọ́ iwaasu Paulu, ati iwaasu awọn alufaa Kristi miiran, ṣugbọn awọn iwaasu naa kò wọ inu ọkàn wọn. Wọn kò fi iye si i, bẹẹ ni wọn kò kọ́ ẹkọ ninu rẹ̀. A maa n digba lo gbolohun yii pe bi ọrọ naa ti n gba etí ọ̀tún wọlé ni o n gba etí òsì jade. Ọrọ ti ẹni naa n gbọ́ kò ṣe e ni ire rara.

### Ṣiṣe Idaro Ara-ẹni

Nigba gbogbo ni a n wá awọn olukọ ti o jafafa ninu Ọrọ Ọlọrun, nitori naa olukuluku gbọdọ bẹrẹ lati maa kọ́ Ọrọ Ọlọrun lẹsẹkẹsẹ ti o bá ti ri igbala ki o ba le ni anfaani lati maa kọ́ awọn ẹlomiran ni aipẹ jọjọ. Ṣugbọn awọn ẹlomiran kò gbiyanju lati kọ́ ẹkọ. Wọ́n n fẹ ki awọn ẹlomiran maa ràn wọ́n lọwọ. Wọ́n sa n fẹ jẹ ọmọ-ọwọ́ titi ti a o maa kọ́ wọn bi a ti n rìn. Dipo ki wọ́n jade lọ bẹ awọn alaisàn wò, ki wọ́n si jẹ́ iranwọ fun awọn ẹlomiran, wọn a joko sinu ile wọ́n a si maa kẹdun ara wọn pe awọn kò ri ki ẹnikẹni wá bẹ awọn wò. Ọna ti o dara jù lọ lati gbagbé awọn wahala rẹ -- bi o bá ni wahala rara – ni ki o wá ẹni kan ti iwọ mọ̀ pé iṣoro rẹ̀ ju ti rẹ lọ ri, ki o si ṣe ohun ti

iwọ le ṣe lati jẹ iranwọ fun un. Iwọ ha ti gbọ́ gbolohun ọrọ yii ri bi, “Emi n sọkun nitori n kò ni bata – titi emi fi pade ẹni ti kò ni ẹsẹ̀”? Njẹ bi a bá ni lati la iṣoro kọja ninu igbesi-ayé wa n kọ́? Oluwa ti ṣe ileri pe Oun yoo wà pẹlu wa lati ràn wá lọwọ. Kò yẹ ki a bẹru nitori ohunkohun.

Ẹ jẹ ki a ṣe bi Kalebu ati Joṣua ti ṣe nigba ti gbogbo awọn amí ti o lọ bẹ ilẹ Kenaani wò n sọkun nitori awọn òmìrán ti wọn rí ni ilẹ naa. Kalebu ati Joṣua wi pe: “Bi OLUWA ba fẹ́ wa, njẹ yio mú wa wọ̀ ilẹ na yi, yio si fi i fun wa; ilẹ ti nṣàn fun warà ati fun oyin” (Numeri 14:8). Eyi ni aṣiiri aṣeyọri Onigbagbọ́: gbigbe irú igbesi-ayé bayii niwaju Ọlọrun. Nigba naa Oun yoo fun ọ ni iṣẹgun nigba gbogbo. “Kò si ohun rere ti yio fà sẹhin lọwọ awọn ti nrin dede” (Orin Dafidi 84:11).

**Igbala Nipasẹ Jesu**

Paulu lo pupọ ninu iwaasu rẹ̀ lati fi ṣe alayé fun awọn Heberu pé Ọmọ Ọlọrun ni Jesu i ṣe ni tootọ. Ṣugbọn ó tún ni ọ̀pọlọpọ nnkan ti o tun n fẹ́ waasu lori rẹ̀. Lati “gbà Jesu Kristi Oluwa gbọ́, a o si gbà ọ là” (Iṣe Awọn Apọsteli 16:31), jẹ́ ibẹrẹ rere fun Onigbagbọ́. Eniyan kò le ri igbala ayafi bi o bá gbagbọ́ pé Ọmọ Ọlọrun ni Jesu i ṣe. Awọn Ju n fi oju sọna si wiwá Messia, ṣugbọn pupọ wọn ni kò gbagbọ́ pe Jesu ni Ẹni naa ti wọ́n n fi oju sọna fún. Nitori naa a kò gbà wọ́n là. “O tọ̀ awọn tirẹ̀ wá, awọn ará tirẹ̀ kò gbà a. Ṣugbọn iye awọn ti o gbà a, awọn li o fi agbara fun lati di ọmọ Ọlọrun, ani awọn na ti o gbà orukọ rẹ̀ gbọ́” (Johannu 1:11, 12). Eyi dara -- ṣugbọn ibẹrẹ ni eyi jẹ́.

**Pípé Onigbagbọ́**

Lẹyin ti a bá ri igbala a gbọdọ lọ si pipe. Eyi bẹrẹ lori isọdimimọ́, eyi ti a maa n saba pe ni pipé Onigbagbọ́. Ifẹ Ọlọrun maa n pọ̀ to bẹẹ ninu ọkàn ti a maa n digba fi wé omi òkun. Olorin kan kọ bayii pe:

**“Gbigbooro bi okun,**
**Giga bi oke ọrun;**
**Jijin bi ọgbun okun,**
**Nifẹ Ọlọrun.”**

A oo maa ni ifẹ Ọlọrun ninu ọkàn wa bi a ti n sin Oluwa si i, ti a si n fi tọkantọkan beere lọwọ Ọlọrun fun gbogbo ibukun wọnni ti O ni lati fun wa. Nigba ti a bá gba ifiwọni Ẹmi Mimọ́ sinu ọkàn ti ó mọ́, ti a ti sọdimimọ́, a oo ni ẹkunrẹrẹ ifẹ Ọlọrun.

Bi awọn eniyan kò bá beere fun awọn ohun ijinlẹ ti Ọlọrun, wọ́n wà ninu ewu nla ti sisọ eyi ti wọ́n ní nù. Alaanu ni Ọlọrun, nigba ti ẹsẹ̀ eniyan bá si yẹ̀ kuro loju ọna Onigbagbọ́ ti o si pada sẹyin, Oun yoo dariji nigbakigba ti irú ẹni bẹẹ bá ronupiwada.

**Lilọ Kuro Ninu Igbagbọ́**

Ṣugbọn awọn miiran wà ti kò le di ẹni ti o fi ẹsẹ mulẹ ninu igbagbọ́. Wọ́n a tún pada sẹyin, wọ́n a tún ṣubu leralera, nikẹyin wọ́n lè jinna si Ọlọrun ninu ifasẹyin wọn dé àye ti Ọlọrun kò ni fi bá wọn sọrọ. Njẹ ki ni yoo ṣẹlẹ bi Ọlọrun kò bá bá wọn sọrọ mọ́ lae? Wọn yoo kuna gbogbo anfaani ati ri igbala. Niwọn igba ti Ẹmi Ọlọrun bá ṣi n dá apẹyindà lẹbi, ireti ṣi wà fun un lati pada sọdọ Oluwa; ṣugbọn nigba ti Ẹmi kò ba tun pe e si ironupiwada mọ́, o ti ṣako jinna – o ti lọ kuro ninu igbagbọ́. Nigbakigba ti eniyan ba pada sẹyin ni o dabi ẹni pe o tún kan Jesu mọ́gi nigba keji. Nitori awọn ẹ̀ṣẹ ti a dá ni Jesu ṣe kú; nitori naa ó daju pé awa kò ni tun fẹ lọ dá ẹ̀ṣẹ mọ́ lẹyin ti a ti ri igbala. Wo bi yoo ti jẹ́ ọ̀ràn ibanujẹ tó fun ẹni ti o ti ri igbala lati pada sẹyin ti yoo si ṣako jinna dé ibi ti Ẹmi Ọlọrun kò tun ni rọ̀ ọ́ mọ́! Awa fẹ jẹ́ ọ̀kan ninu awọn wọnni ti Paulu sọ nipa wọn, awọn ti o “ti ipa igbagbọ́ ati sũru jogún awọn ileri.” Ninu ẹkọ ti a oo ṣe niwaju a oo sọ ni kinnikinni nipa ohun ti awọn ileri wọnyii jẹ́.

## AWỌN IBEERE

1. Ki ni ounjẹ ti a kọkọ maa n fi fun awọn ọmọ-ọwọ́ jẹ?
2. Ki ni yoo tún maa jẹ nigba ti ó bá dagbà diẹ si i?
3. Awọn wo ni ọmọ-ọwọ́ ninu Kristi?
4. Bawo ni awọn ọmọ-ọwọ́ ninu Kristi ṣe lè dagba soke?
5. Ọna wo ni Kalebu ati Joṣua fi gbà yatọ si awọn amí iyoku?
6. Ki ni igbẹkẹle wọn fun gbigba ibukun Ọlọrun?
7. Ki ni yoo ṣẹlẹ nigba ti eniyan bá jẹ́ ẹni ti n pada sẹyin nigbakuugba?
8. Bawo ni a ṣe le ri awọn ileri Ọlọrun gbà?